“Iná yin jẹ ẹyà kan nínú ẹyà àádọ́rin ti ina Jahannama ni

Láti ọdọ́ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- pé Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe: “Iná yin jẹ ẹyà kan nínú ẹyà àádọ́rin ti ina Jahannama ni”, wọn sọ pé: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, iná ayé gan ti tó. O sọ pe: “Ina Jahannama ju ti aye lọ pẹ̀lú ẹyà mọkandinlaadọrin, gbígbóná ọkọọkan ninu ẹ da gẹgẹ bii gbígbóná iná ayé”.
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun o maa ba a, sọ fun wa pe ina aye yii jẹ ọkan ninu aadọrin awọn ẹya ina Jahannama, Gbígbóná iná ọjọ́ ìkẹyìn lágbára ju gbígbóná iná ayé lọ pẹ̀lú ẹyà mọkandinlaadọrin, ẹyà kọ̀ọ̀kan nínú rẹ̀ ṣe déédéé gbígbóná ina ayé. Wọ́n sọ pé: Ìwọ Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun, iná ayé yìí ti tó láti fi fi ìyà jẹ àwọn ti wọn ba wọ́ ọ́, O sọ pé: Ina Jahannama ju ina ayé lọ pẹ̀lú ẹyà mọkandinlaadọrin, ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú rẹ̀ da gẹgẹ bii rẹ nibi gbígbóná gidi gan.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65036

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee